EFF'S SURVEILLANCE SELF-DEFENSE

# LÍLO ALÁKÒÓSO ỌRỌ-ÌFIWỌLÉ FÚN ÌṢẸDÁ ỌRỌ-ÌFIWỌLÉ TÓ LÁGBÁRA

*https://ssd.eff.org/en/about-surveillance-self-defense*

LOCALIZATION LAB

**Lílo Alákòóso Ọ̀rọ̀-Ìfiwọlé fún Ìṣẹ̀dá Ọ̀rọ̀-ìfiwọlé tó Lágbára**

Àtúnùntúnlò ọ̀rọ̀-ìfiwọlé jẹ́ ọ̀nà ààbò tí kò dára. Bí òṣèré ibí bá gbá ọ̀rọ̀-ìfiwọlé tí o ti tún lò lórí ọ̀pọ̀lọpọ̀ iṣẹ́ mú, wọ́n lè r'ọ́nà wọ inú ìṣàmúlò rẹ. Torí ìdí èyí ni ó fi dára tí ó sì pọn dandan kí a ní ọ̀pọ̀lọpọ̀ ọ̀rọ̀-ìfiwọlé tó lágbára, tó sì yàrà ọ̀tọ̀.

Ní rere, alákòóso ọ̀rọ̀-ìfiwọlé lè ṣerànwọ́. Alákòóso ọ̀rọ̀-ìfiwọlé ni irinṣẹ́ tí í máa ń ṣẹ̀dá àti fi ọ̀rọ̀-ìfiwọlé pamọ́ fún ọ, kí o ba lè lo onírúurú ọ̀rọ̀-ìfiwọlé lórí onírúurú ibùdó-ìtàkùn-àgbáyé láì sí wípé ó há a s'ágbárí.
Alákòóso ọ̀rọ̀-ìfiwọlé:

- Máa ń ṣàgbajáde ọ̀rọ̀-ìfiwọlé tó ṣòro fún ọmọ-ènìyàn láti mọ̀.
- Máa ń fi ọ̀gọ̀rọ̀ ọ̀rọ̀-ìfiwọlé sí ìpamọ́ (àti èsì fún ìbéèrè ààbò) pẹ̀lú ààbò tó péye.

**Dáàbò bo ọ̀rọ̀-ìfiwọléè rẹ pẹ̀lú ọ̀rọ̀-ìfiwọlé olúwa (tàbí gbólóhùn ìfiwọlé ọlọ́rọ̀ kan)**

KeePassXC ni irúfẹ́ alákòóso ọ̀rọ̀-ìfiwọlé tó jẹ́ irinṣẹ́ ìṣísílẹ̀ ọ̀fẹ́. O lè tọ́júu irinṣẹ́ yìí sórí ẹ̀rọ-ayárabíàṣá àgbélétábìlì rẹ tàbí kí o fi s'ínúu aṣàwákiri ibùdó-ìtàkùn rẹ. KeePassXC kì í fi àyípadà tí o bá ṣe nígbà tí o bá lò ó pamọ́ fúnra rẹ̀, bí ó bá d'aṣẹ́ sílẹ̀ lẹ́yìn tí o ti fi ọ̀rọ̀-ìfiwọlé kún tilẹ̀, o lè pàdánùu rẹ títí láéláé. O lè yí èyí padà nínú ààtò.

Ò ń gbèrò bóyá alákòóso ọ̀rọ̀-ìfiwọlé ni irinṣẹ́ tó tọ́ sí ọ? Bí ọ̀tá ńlá bíi ìjọba bá ń lépaà rẹ, o lè máà jẹ́ bẹ́ẹ̀.

Rántí:
- Lílo alákòóso ọ̀rọ̀-ìfiwọlé máa ń ṣẹ̀dáa ìkúnnà kan ṣoṣo.
- Alákòóso ọ̀rọ̀-ìfiwọlé jẹ́ ìlépa gbangba fún ọ̀tá.
- Ìwádìí ṣíni níyè wípé ọ̀pọ̀lọpọ̀ alákòóso ọ̀rọ̀-ìfiwọlé ni ìpalára lè bá.

Bí ọkàn-an rẹ kò bá balẹ̀ lórí ìdojúkọ orí ẹ̀rọ ayárabíàṣá olówó iyebíye, o lè lo èyí tí kò gba wàhálà púpọ̀.
O lè ṣẹ̀dá ọ̀rọ̀-ìfiwọlé àfọwọ́ṣe (wo "bí a ṣe ń lo dice fún ìṣẹ̀dá ọ̀rọ̀-ìfiwọlé alágbára" nísàlẹ̀) kọ ọ́ sílẹ̀, kí o tọ́júu rẹ̀ síbi tó l'ààbò.

Dúró, ṣe àgbárí kọ́ ni ó yẹ kí a há ọ̀rọ̀-ìfiwọlé sí àti kí a máa kọ ọ́ sílẹ̀ rárá? Lóòótọ́, kò burú bí a bá kọ ọ́ sílẹ̀, kí a sì fi pamọ́ síbìkan bí àsùnwọ̀n ìkówósí àfisápò rẹ, èyí yóò ta ọ́ jí b'ọ́rọ̀-ìfiwọlé tí o kọ sílẹ̀ bá di àwátì tàbí bí wọ́n bá jí i.

## Bí a ṣe ń lo dice fi ṣẹ̀dá ọ̀rọ̀-ìfiwọlé alágbára

Ó ní àwọn ọ̀rọ̀-ìfiwọlé alágbára tí ó yẹ kí o há s'ágbárí. Àwọn ni:

- Ọ̀rọ̀-ìfiwọlé fún ẹ̀rọọ̀ rẹ

-Ọ̀rọ̀-ìfiwọlé fún ìyí-dátà-padà-sí-odù-ààbò (bíi ìyí-dátà-padà-sí-odù-ààbò dîìskì kíkún)
-Ọ̀rọ̀-ìfiwọlé olúwa, tàbí gbólóhùn ìfiwọlé ọlọ́rọ̀ kan, fún alákòóso ọ̀rọ̀-ìfiwọléè rẹ
- Ọ̀rọ̀-ìfiwọlé ímeèlì rẹ.

Ìṣòro kan tí àwọn èèyàn bá ń yan ọ̀rọ̀-ìfiwọlé fúnra wọn ni pé àwọn èèyàn kò mọ̀ bí a ṣe ń ṣe àṣàyàn láìròtẹ́lẹ̀ àti aláìsọtẹ́lẹ̀. Ọ̀nà ìṣèdá ọ̀rọ̀-ìfiwọlé tó lágbára tí ó sì ṣe é rántí jù ni bí a bá lo dice àti àkàsílẹ̀ ọ̀rọ̀ láti yan ọ̀rọ̀ láìròtẹ́lẹ̀. Lápapọ̀, àwọn ọ̀rọ̀ wọ̀nyí ni "gbólóhùn ìfiwọlé ọlọ́rọ̀ kan." "Gbólóhùn ìfiwọlé ọlọ́rọ̀ kan" ni irúfẹ́ ọ̀rọ̀-ìfiwọlé aláàbò tó máa ń gún. Fún ìyí-dátà-padà-sí-odù-ààbò dîìskì àti alákòóso ọ̀rọ̀-ìfiwọléè rẹ, ó kéré jù, yan ọ̀rọ̀ mẹ́fà.

Kí ni ṣe tí ó fi yẹ kí o lo ọ̀rọ̀ mẹ́fà? Kí ní dé tí ó fi yẹ kí o fi dice ṣe ìṣàjọ ọ̀rọ̀ onígbólóhùn kan láìròtẹ́lẹ̀? Bí ọ̀rọ̀-ìfiwọléè rẹ bá ṣe gùn tó ni kò ní fi mú u rọrùn fún ẹ̀rọ ayárabíàṣá àti ènìyàn láti làmọ̀, fídíò alálàyé kan rè é.

Gbìyànjú kí o lo àṣàkalẹ̀ ọ̀rọ̀ EFF láti ṣe gbólóhùn ìfiwọlé ọlọ́rọ̀ kan.

Bí adojúkọ bá dojúkọ ẹ̀rọ ayárabíàṣáà rẹ tàbí ẹ̀rọọ̀ rẹ, tí iṣẹ́-àìrídìmú alamí wà lórí rẹ̀, iṣẹ́-àìrídìmú alamí lè máa wò ọ́ bí o bá ń tẹ ọ̀rọ̀-ìfiwọlé olúwaà rẹ. Torí náà ó pọn dandan kí ẹ̀rọ ayárabíàṣáà rẹ àti ẹ̀rọọ̀ rẹ ó wà ní mímọ́, kí o máà sí iṣẹ́-àìrídìmú àìdára bí o bá ń lo alákòóso ọ̀rọ̀-ìfiwọlé.

## Ọ̀rọ̀ nípa "ìbéèrè ààbò"

Kíyèsára fún "ìbéèrè ààbò" tí ibùdó-ìtàkùn-àgbáyé ń lò fi ṣe ìfẹsẹ̀múlẹ̀ ìdánimọ̀ọ rẹ.
Ìdáhùn òdodo sí ìbéèrè wọ̀nyí máa ń wà ní àrọ́wọ́tóo gbogboògbò tí yóò sì gbé ẹ̀rí tí ọ̀tá lè lò fi fo ọ̀rọ̀-ìfiwọléè rẹ kọjá yányán.

Kàkà bẹ́ẹ̀, fi ìdáhùn tí kì í ṣe òdodo pọ́nbélé tí ẹnìkan yàtọ̀ sí ìrẹ kò mọ̀ sílẹ̀. Fún àpẹẹrẹ, bí ìbéèrè ààbò bá ní:

"Kí ni orúkọ ẹranko ilé tí o fẹ́ràn àkọ́kọ́ọ̀ rẹ?"

Idáhùn rẹ lè jẹ́ ọ̀rọ̀-ìfiwọlé aláìròtẹ́lẹ̀ tí alákòóso ọ̀rọ̀-ìfiwọléè rẹ gbàjáde. O lè fi ìdáhùn àìṣòdodo pọ́nbélé wọ̀nyí s'ínúu alákòóso ọ̀rọ̀-ìfiwọléè rẹ.

Ronú nípa ibùdó-ìtàkùn tí o ti lo ìbéèrè ààbò rí kí o sì gbèrò nípa ìyípadà èsì rẹ. Máà lo ọ̀rọ̀-ìfiwọlé tàbí ìbéèrè ààbò kan náà fún gbogbo ìṣàmúlò fún gbogbo ibùdó-ìtàkùn-àgbáyéè tàbí iṣẹ́.

## Ìmúṣiṣẹ́pọ̀ ọ̀rọ̀-ìfiwọléè rẹ lórí ẹ̀rọ gbogbo

Ọ̀pọ̀ alákòóso ọ̀rọ̀-ìfiwọlé ń fi ààyè gba ọ̀rọ̀-ìfiwọléè rẹ lórí gbogbo ẹ̀rọ - nípa àmúṣiṣẹ́pọ̀. Èyí ni pé bí o bá mu ọ̀rọ̀-ìfiwọléè rẹ ṣiṣẹ́ pọ̀ lórí ẹ̀rọ kan, yóò ṣàfikún lórí ẹ̀rọ ìyókù.

Alákòóso ọ̀rọ̀-ìfiwọlé lè fi ọ̀rọ̀-ìfiwọléè rẹ pamọ́ "s'ínúu kùkukùru," tí ó túmọ̀ sí wípé a ti yí dátà rẹ padà sí odù ààbò sínú apèsè àrọ́wọ́tó. Bí o bá nílòo ọ̀rọ̀-ìfiwọléè rẹ, alákòóso ọ̀rọ̀-ìfiwọlé wọ̀nyí yóò ṣe àgbàjáde ọ̀rọ̀-ìfiwọlé, yóò sì tú ọ̀rọ̀-ìfiwọlé tí a ti yí padà sí odù ààbò fúnra rẹ̀.
Alákòóso ọ̀rọ̀-ìfiwọlé tí ń fi apèsèe tirẹ̀ ṣe ìpamọ́ tàbí ìrànwọ́ àmúṣiṣẹ́pọ̀ ọ̀rọ̀-ìfiwọléè rẹ rọrùn bíi kààsínǹkan, ṣùgbọ́n ìpalára ìdojúkọ lè bá wọn.
Bí o bá fi ọ̀rọ̀-ìfiwọléè rẹ pamọ́ sí orí ẹ̀rọ ayárabíàṣá àti s'ínúu kùkukùru, adojúkọni kò ní í lo ẹ̀rọ ayárabíàṣáà rẹ láti mọ ọ̀rọ̀-ìfiwọléè rẹ. (Wọ́n ní láti fọ́ gbólóhùn ìfiwọlé ọlọ́rọ̀ kan ti alákòóso ọ̀rọ̀-ìfiwọléè rẹ.)

Bí èyí bá kàn ọ́ gbọ̀ngbọ̀n, máà mú ọ̀rọ̀-ìfiwọléè rẹ ṣiṣẹ́ pọ̀ s'ínúu kùkukùru, kàkà bẹ́ẹ̀ fi wọ́n pamọ́ sórí ẹ̀rọọ̀ rẹ.

Tọ́júu ìkópamọ̀ ilée dátà ọ̀rọ̀-ìfiwọléè rẹ torí aìíṣeémọ̀. Àkópamọ́ wúlò bí o bá pàdánù ilé dátà ọ̀rọ̀-ìfiwọléè rẹ látàrí ìdaṣẹ́sílẹ̀, tàbí tí ẹ̀rọọ̀ rẹ bá di jíjí.
Alákòóso ọ̀rọ̀-ìfiwọlé sábà máa ń ní ọ̀nà láti ṣe àkópamọ́ fáìlì, tàbí kí o lo iṣẹ́ àkópamọ́ tó wọ́pọ̀.

## Ìfẹ̀rílàdí Ọlọ́nà púpọ̀ àti ọ̀rọ̀-ìfiwọlé ẹ̀rìnkan

Ọ̀rọ̀-ìfiwọlé alágbára, aláràọ̀tọ̀ kì í mú u rọrùn fún òṣèré ibi láti r'áàyè wọ ìṣàmúlò rẹ fún ìfẹ̀rílàdí ọlọ́nà méjì.

Àwọn iṣẹ́ kan a máa fún ni ìfẹ̀rílàdí ọlọ́nà méjì (tí a tún ń pè ní 2FA, ìfẹ̀rílàdí ọlọ́nà púpọ̀ tàbí ìfẹ̀rílàdí ìgbésẹ̀ méjì), tí òǹlò gbọdọ̀ lo ohun méjì (ọ̀rọ̀-ìfiwọlé àti ọ̀nà mìíràn) láti r'áàyè wọ ìṣàmúlò wọn. Ọ̀nà kejì lè jẹ́ odù alálòlẹ́ẹ̀kan tàbí òǹkà tí ẹ̀rọ alágbèéká gbàjáde.

Ọ̀nà méjì ni a lè fi ṣe ìfẹ̀rílàdí ọlọ́nà méjì lórí ẹ̀rọ-ìbánisọ̀rọ̀ alágbèéká:

Ẹ̀rọ-ìbánisọ̀rọ̀ọ rẹ lè ṣiṣẹ́ ìfẹ̀rílàdí láti ṣe àgbájáde odù ààbò (gẹ́gẹ́ bíi Afẹ̀rílàdí Google tàbí Authy) tàbí kí o lo ẹ̀rọ iṣẹ́ àìrídìmú àládààdúró (gẹ́gẹ́ bíi YubiKey); tàbí
Iṣẹ́ náà lè fi àtẹ̀jíṣẹ́ SMS pẹ̀lú àfilé odù ààbò tí ó ní láti tẹ̀ nígbàkúùgbà tí o bá fẹ́ wọlé.

Kàkà kí o gba àfilé odù ààbò, o lè yan iṣẹ́ ìfẹ̀rílàdí tàbí ẹ̀rọ iṣẹ́-àìrídìmú àládààdúró. Ó rọrùn fún adojúkọni láti ṣ'àtúndarí odù wọ̀nyí sórí ẹ̀rọ-ìbánisọ̀rọ̀ọ ti wọn ju ìdákọjá afẹ̀rílàdí lọ.

Àwọn iṣẹ́ kan, gẹ́gẹ́ bíi Google, náà máa ń f'àáyè gbà ọ́ láti ṣ'àgbàjáde àkàsílẹ̀ ọ̀rọ̀-ìfiwọlé ẹ̀rìnkan ṣoṣo, tí a tún ń pè ní ọ̀rọ̀-ìfiwọlé alálòlẹ́ẹ̀kan. Ó yẹ kí a tẹ̀ ẹ́ sórí ìwé tàbí kọ ọ́ sílẹ̀ kí a máa gbé e kiri. Ẹ̀ẹ̀kan ṣoṣo ni ọ̀kọ̀ọ̀kan ọ̀rọ̀-ìfiwọlé wọ̀nyí ń ṣiṣẹ́, torí náà bí iṣẹ́-àìrídìmú alamí bá jí ọkàn, olè náà kò ní le è lò ó fún ohunkóhun lọ́jọ́ iwájú.

Bí ìwọ tàbí ilé-iṣẹ́ẹ̀ rẹ bá ní irinṣẹ́ ìtàkùrọ̀sọ tirẹ̀, iṣẹ́-àìrídìmú ọ̀fẹ́ wà lárọ̀ọ́wọ́tó tí ó ṣe é lò láti f'àáyègba ìfẹ̀rílàdí ọlọ́nà méjì láti r'áàyè wọ ẹ̀rọọ̀ rẹ. Wá iṣẹ́-àìrídìmú tí ó jẹ́ ti ìṣísílẹ̀ "Ọ̀rọ̀-ìfiwọlé Ẹ̀rìnkan ṣoṣo Adálórí Àkókò" tàbí RFC 6238.

## Nígbà mìíràn, O Ní láti Sọ Ọ̀rọ̀-ìfiwọléè Rẹ

Òfin nípa sísọ ọ̀rọ̀-ìfiwọlé yàtọ̀ láti ibìkan dé òmíràn. Nígbà mìíràn o lè kọ̀ jálẹ̀ kí o máà fún ẹnikẹ́ni ní ọ̀rọ̀-ìfiwọléè rẹ, níbo mìíràn ẹ̀wẹ̀wẹ̀ òfín ìbílẹ̀ f'ààyè gba ìjọba láti béèrè fún ọ̀rọ̀-ìfiwọlé ẹnikẹ́ni - àti pàápàá fi ọ́ sí àtìmọ́lé bí o bá jẹ́ afurasí tí ó mọ ọ̀rọ̀-ìfiwọlé tàbí kọ́kọ́rọ́ kan. A lè lo ìdẹ́rùbà ìpalára ojúkorojú láti fi gba ọ̀rọ̀-ìfiwọlé lọ́wọ́ èèyàn. Tàbí kí o bá araà rẹ nínú ìṣẹ̀lẹ̀ kan, bíi rírin ìrìn àjò s'ódìkejì ìlú, níbi tí àwọn aláṣẹ lè ti dá ọ dúró tàbí gba ẹ̀rọọ̀ rẹ bí o bá kọ̀ láti fún wọn ní ọ̀rọ̀-ìfiwọlé tàbí ṣí ẹ̀rọọ̀ rẹ.